# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA
No. 1,432 WEDNESDAY AUGUST 18, 1965 (2d)


## Enia Marun Ku Ninu Ijamba Moto

ONITSHA.— Ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ ketala ọṣu yi ni Irohin kan de ọwọ wa pe enia marun padanu ẹmi wọn ninu Ijamba moto kan to ṣelẹ ni ọna Onitsha si ọna Enugun eyiti o fi jẹ wipe enia medogun lo fi ara gbọgbẹ ninu awọn enia to wa ni nu moto na, ninu awọn enia to fi ara gbọgbẹ ni Dẹrẹba moto na pelu ọmọ-iṣẹ rẹ.

Irohin awọn Ọlọpa ti ilu Onitsha fi ye wa pe enia meji lo ku bamubamu nibiti Ijamba moto na ti ṣẹlẹ ti awọn enia yoku si tun ku nigbati o ku diẹ ki nwọn gbe wọn de ile Iwosan ti nwọn yio ti ṣe itọju wọn.

Ninu awọn ti o fi ara gbọgbẹ ninu Ijamba moto na ni a gbọ wipe nwọn ti mọ oruko awọn enia meji ninu wọn awọn ti nwọn mọ orukọ rẹ na ni Ọgbẹni Stephen Egbo ti o ku kan ti nwọn npe ni Ichi eniti iṣe ọmọ ọgbọn ọdun ati Okpe ti iṣe ẹni ọdun mejidin logbon.

Irohin awọn Ọlọpa fi ye wa pe nigbati moto bọọsi na lọ si Onitsha lati ilu Enugun ni iṣẹlẹ nla na ti ṣelẹ ti moto na si fi ori lọ sọ igbo nla kan to wa ni ọna na.

WO OJU EWE KẸFA

# IJỌBA KO FẸ GBỌ ORIN OLOYE AWOLỌWỌ MỌ

AGEGE:- Agba iyanu nla ni Irohin ti o kan gbogbo awọn enia ku ninu ọsẹ ti o kọja lọ yi jẹ nigbati awon enia na gbele gbo wipe, Ijoba Ibilẹ Agege ti ṣe Ofin kan ninu ipade ti nwon ṣe ni osẹ ti o koja lo yi wipe awon ko tun gbodo gbo ki ẹnikan tun ko Orin awo Rẹkodu Oloye Ọbafẹmi Awọlowo. O l o r i ẹgbẹ Afẹnifẹre, ẹniti o wa ni ọgba ẹwon Kalaba nisisiyi.

Agboroso Ijoba kan so ninu ile iṣẹ Minista Alamojuto eto Ijoba Ibilẹ ni Ibadan ni opin osẹ ti o koja lo yi wipe, ninu ipade ti awon alaṣẹ Ijoba Ibilẹ agbegbe Agege ṣe ninu osẹ na ni gbogbo awon omo ile Igbimo na ti so wipe awon ko tun fẹ gbo ki ẹnikan tun'ma a ko orin tabi maa lu awo rẹkodu Oloye Ọbafẹmi Awolowo mo.

Awọn alaṣẹ Ijọba Ibilẹ na sọ wipe, bi awon ba tun gbo ti ẹnikan ba tun le kọ orin Oloye Awolowo na ninu ilu, awon Ọlopa yio mu Oluware, nwon yio si ba a ṣe ẹjọ.

Ṣugbọn nigbati nwọn ba mu oluwarẹ de ile ẹjọ, oluwarẹ yio jẹbi ẹsun na, yio si fi ọgbọn pọnun (£30) tanran si kotu, tabi ki oluwarẹ lọ fi ẹwọn oṣu mẹfa jura.

Irohin na tun sọ siwaju wipe, ẹnikẹni ko tun gbọdọ kigbe wipe, "A ... O!" mọ ni gbogbo arin ilu Agege ki awọn gbọ, ti ẹnikan ba si tẹ ofin titun na leti, ki oluwarẹ mọ wipe on ti lugbadi ofin Ijọba eyiti yio lọ fi owo tanran ni ile ẹjọ fun tabi ti yio lọ fi ẹwọn oṣu mẹfa jura fun.

Onirohin wa kan ti i ma a wadi okodoro ọro ti o lọ si Agege ni irolẹ a a fi ye wa wipe siwaju asiko na ni gbogbo awọn ara ilu na maa nkọrin Oloye Awolọwọ.

Bi awon enia na ba wa ni-

WO OJU EWE KẸFA



**Oloye Ọbafẹmi Awolowo**
Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre.

# ORO OLOTU

## TALO RAN AWON OLUKO NI'SE?

Awon Yoruba ni bi e'gun eni ba njo re, ori ma a ya atokun re. Gege be ni oro ti awa Oniwe Irohin Imole fe ba awon Oluko ati awon alase eto eko fun Apapo Ijoba Naijiria so ninu iwe wa ni Owuro yi nipa eto ti awon enia na se fun awon emode ti nwon ti beresi lo fi oruko won sile fun eto eko ofe fun odun ti nbo yi 1966.

Lati kutukutu owuro ije'a ojo Aje ti ise ojo kerindinlogun osu yi ni gbogbo awon obi ti nwon fe fi oruko awon omo won sile ti beresi ma mu awon omo won lo si ile iwe ti nwon fe ki omo won lo ninu odun ti nbo yi ti nwon si nfi oruko awon omo won sile.

Awon Oluko na se ise won dara ju ti odun ti o koja yi lo, ko si idarudapo kankan gegebi ti odun ti o lo yi Sugbon ohunti o se awa Oniwe Irohin Imole ni aanu nipe opolopo awon Obi ni nwon lo sun si ibiti nwon gbe fe fi oruko awon omo won sile Awon elomiran gbe eni lowo lo ti nwon si lo sun sibe titi di ojo keji lati ojo Aiku ti ise ojo kedogun osu yi ninu otutu ati ategun buruku ti nfe larin oru yi.

Sugbon ohunti o ya awa Oniwe Irohin lenu ninu oro na ni Irohin ti a gbo ni ana wipe awon akowe ti nwon nfi oruko awon omode na sile nbere lowo nwon Obi bi awon omo won ti se tobi to? Eyi je ohunti o ya awa Oniwe Irohin Imole lenu lopolopo nigbati a gbo Irohin na ti awon Obi omo nso.

Awa Oniwe Irohin Imole wa kesi Ogbeni Richard Akinjide ti ise Minista Alamojuto eto eko fun apapo Ijoba lati te e so fun gbogbo araiye gbo eniti o ba fi ise oro na ran awon Oluko ti nwon nfi oruko awon omo sile lati ma tun bere bi awon omo ti se tobi to owo awon obi won ki nwon to le fi Oruko awon omo na sile

Gegebi alaye ti awon alase eto eko na ti koko se fu gbogbo awon Obi ni Eko gbo ni wipe, nka meta pe e ni awon fe ki awon Obi omo ti nwon ba fe fi oruko awon omo won sile mu lowo ti nwon ba nbo wa fi oruko awon omo won sile awon nkan meteta na ni:

(1) Awon Obi gbodo mu iwe ojo'bi omo won lowo lo si ibiti nwon fe gbe fi oruko omo won sile tabi ibiti nwon fe ki omo won lo si ile iwe ni odun ti mbo.

Awon obi gbodo mu iwe ti nwon gba nigbati nwon ko i omba fun omo won nitori arun iba ponjuponju lowo lo si ibiti nwon fe gbe lo fi oruko awon omo won sile fun eko-ofe ki nwon si fun awon akowe ti nwon ba ni ibiti nwon fe gbe fi oruko awon omo won sile,

Awon obi gbodo ya aworan omo won, ki nwon si mu meta ninu awon aworan kekeke na lowo lo si ibiti yio gbe fi oruko awon omo won sile ni ojo na ki awon akowe na si leri awon nkan wonyi.

Eyi ni awon nkan meta ti awon alase eto eko bere lowo awon obi wipe ki nwon mu lowo nigbati nwon ba ngmu omo won lo si ibiti nwon yio gbe fi oruko omo won sile.

Sugbon nigbati awon obi mu omo won de ibiti nwon gbe fe fi oruko awon omo won sile, awon Oluko kan nbere lowo awon Obi na wipe, Bawo ni omo re nati tobi tabi wuwo to? owo awon Obi lehinti nwon ba ti bere, ti nwon si gba gbogbo awon nkan meteta ti Ijoba ran won tan lowo awon Obi na tan.

Awon ti nwon ko ba le so bi omo won ti se tobi tabi wuwo to, nwon nle won pade sehin wipe, "Iwo ko lo maa lo, omo ma gbe yen wa o," Inu awa oniwe Irohin Imole yio dun lopolopo ti Minista Alamojuto eto eko ba le se iwadi oro na wo ni owuro yi, ki nwon si mo awon ti nwon nje ise ti Ijoba ko ran won ninu awon "Tisa alaimokan" ti nwon nhu iru iwa palapala na, ki nwon si da iru seria ti o ba to fun won ki o le je arikogbon fun awon elomiran ti nwon ba tun ni ife ati maa se ohunti nwon ba fe yato si ise ti nwon ran won.

Sugbon ki Ijoba to se iwadi na ki nwon si to mo nwon oluko na, awa oniwe Irohin Imole bere lowo won wipe, "Talo ran awon oluko nise?.

# YEYENATU

## ONIYEYE EKO

Yeyenatu: Olotu howu nibo ni e lo ti a ko ri nyin nile?

Olotu: Ibadan ni.

Yeyenatu Kini se ti e ko lo si Abeokuta ilu nyin.

Olotu: Nitoripe e yin omo Ibadan kilo Ibadan ni

Yeyenatu: Ohun ti oba wun yin e wi Ibadan ki ise egbe Abeokuta.

Olotu: Lojo ti re ni- O dara gomina meloni o wa ni Abeokuta?

Olotu Ki nto le dahun iwo na so fun mi Oba melo ni O wa ri Ibadan?

Yeyenatu He ro pe gbo gbe ilu lo dabi Abeokuta ti oni Oba bi merin in?

Olotu Ajulo ni nyen.

Yeyenatu Ajulo ni ki Oba medogbon wa ni ilu kan sa

Olotu Koye e ni oto ni ake oteni Ibara oloni Owu

Yeyenatu Bi o ba jehe awa na ni O a meji Ibadan

Olotu Yeyenatu iro ko ni pa o?

Yeyenatu Tani emi o dara se Olubadan kise Oba

Olotu: Eni

Yeyenatu Se Kabiyesi Akran ki ise Oba

Olotu Yes Oba Badagri ni ke ki ise ti Ibadan.

Yeyenatu: Oba ibi ti nwon je ko ni mo bere. Se Oba ni nwon sa?

Olotu: Yes

Yeyenatu; Se Ibadan ni nwon si wa?

Olotu: Yes

Yeyenatu: Nitorina e ko le se faari si aOa ara Ibadan ra rara

Olotu: Nko mo pe o ti d. Loya

Yeyenatu: Se e fe bo mi ni?

Olotu: Aiya re nja ni? Loya Ibadan

Yeyenatu; E sa ti so pe

Olotu: So pe k ni?

Yeyenatu: Aiya tiyin na nja ni?

Olotu: Ha! iwo ko mo pe ogbon ni agba fi nsa fun maalu?

Yeyenatu: Bawo Sebi a ti mo yin ni olowo

Olotu: Se owo ti nya bi aso yi?

Yeyenatu: Igbati o da bayi ra ni

Olotu; Igbati o da bawo? Iwo ro pe emi le se ni, emi ki i se ilu, ma ko ba mi o



Yeyenatu: Nje mo tile so fun nyin

Olotu: Pe kini?

Yeyenatu: Pe awa omo Ibadan fe lo p ri ija larin awon egbe NNDP

Olotu; O ko so, Iyen ma d ra n toripe alabukun ni awon onilaja. Tani da ija sarin won?

Yeyenatu: Alajobi ni.

Olotu: O mase o, Bwo lo se mo?

Yeyenatu: Se e ri ojo ti o ro ni Ijelo

WO OJU EWE KARUN

## Iwe si Olotu Irohin Imolẹ

### Ẹ FI EYI S'ERO

Olotu, Jọ'ọ gba mi laye diẹ ninu Iwe aladun rẹ ti Ogunlọgo eni ma a nka rẹlu inu dundun lati sọ fẹ, ki MINISTA ẸKỌ ṣe e ni ofin fun awọn olukọ pe, ki nwọn ma a ṣe iwe ẹri ti yio ma a fi bi nwọn tiṣe nṣe ṣe wọn si han lọsọọsẹ (Weekly Report Card).

Eyi ti nwọn yio ma a fi han awọn obi wọn.

Nipa bayi, awọn Olukọ ati awọn obi yio wa ni ifọwọsọwọpọ lati ma a bojuto awọn ọmọ akẹkọ na daada.

Awọn ọmọ na yio si ma a ni ilosiwaju ninu ẹkọ ati iwa wọn.

Emi ni
Alhadji Awaiyewaṣere
EKO.

### Mo Dupẹ Lowo Ẹgbẹ Anjorin

Olotu inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin to kun fun ọgbọn ati oye lati dupẹ lọwọ awọn ẹlẹgbẹ mi ti a npe ni ẹgbẹ Anjorin ti ilu Omupo lori inawo ayẹyẹ kan ti mo se fun awọn ọmọ ẹgbẹ na ni ọjọ kẹjọ oṣu yi.

Mo tun kan saara si Alhaji Igbo-Owo ti o jẹ oni lu ojo na eyiti o fi ilu rẹ na gbogbo awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na laraya, mo tun dupe lowo baba Gani ti iṣe omo Ilala fun inawo ojo na be ẹ ni akowe ẹgbẹ Anjorin ẹgbẹni Sanni Asanda, Olotu e ṣe pupọ fun aye ti e gba mi oko Ọba ko ni ṣa gyin lese o,

Emi ni
Babatunde Aremu
Eko

### Ọmọ Ilu Offa Ẹ Ronu Nyin

Olotu jọwọ gba mi ni aye ranpẹ ninu iwe nyin to kun fun ọgbọn ati oye lati kesi awọn enia ilu Ọffa nipa ohunti o tọ ki awọn ṣe ti awọn sikuni lati ṣe awọn

nkanna eyiti iṣe nipa ẹniti o yẹ ki a dibo wa fun lọdun ti o kọja ti a si kuna ati dibo wa fun ẹniti i oyẹ ki a dibo wa fun

Mo ro pe lẹhin ti a dibo wa fun ẹgbẹ Olomi bayi a ti fi oju ara wa ri pe ko si ilọsiwaju kankan ti ẹniti a dibo na fun se fun wa ati pe yio si jẹ ohunti o buru lati tori owo ko omo iya wa silẹ ki a lo ta ara wa fun alejo.

Ṣugbon mo fẹ ki ẹ jẹki a lo ro nu wa jinle ninu Ibo ti ipinlẹ Ariwa to mbo yi ki a si dibo wa fun eniti o to ti o si yẹ lati dibo na fun eyiti yio jẹki eto alafia ati ilosiwaju le wa fun wa lẹhin ti a ba wole. Olotu mo dupẹ fun aye ti e gba mi.

Emi ni
B. Ọla Alamu

OFFA

### Eleyi Nfẹ Amojuto Ijoba Ibilẹ Ila

Inu mi yio dun bi Olotu Irohin Imọlẹ ba le gba mi ni aye ranpẹ ninu iwe Irohin Imọlẹ to kun fun ọgbọn ati oye lati kesi Ijọba ibilẹ ilu Ila-ọrangun ki nwọn ba wa mu oju to inu ohunti o nṣẹ lọ larin awọn Obinrin ilu na ti nwọn ti nwọn ti ni ọkọ nwọn si nta ẹmu ni ilu Ibadan

Ọpọlọpọ ninu awọn Obinrin na ni ko mu ọkọ lọwọ tabi ba ọkọ rẹ wa si Ibada bẹẹni awọn Obinrin miran ba ọkọ rẹ wa ti nwọn yio jijọ ma lọ si oko ẹmu Ṣugbọn awọn Obinrin miran yio fi ọkọ rẹ si ilu oko ibiti nwọn ti lọ da ẹmu ti yio pada si arin ilu

## Bọ Lọwọ Oṣo Ati Ajẹ

Iwe egbogi Ajẹbidan 25/- mejila £2
Iwe Ilana Ifa Iyanrin titẹ ati etutu rẹ pẹlu Iwosan 20/- mejila £2 5/
Iwe Egbogi Awogba Arun meji 40/-
Turari isẹgun Ajẹ Oṣo ati awọn abinije O wa fun itaja pẹlu alakala Pangolo 10/6 Pakẹti 2/- Ki iṣe ti ẹnu fifọn bi o ra ninu awọn ọja yi aabo ti o nfpọn ni ile aiye ni yio wa lori rẹ ati awọn ẹbi rẹ

Fi owo ranṣẹ si

J O SHOYINKA
5 Alaabe Stre,
Odu abọn Mush

GBANGBA DẸKUN KEDERE BẸWO !! BI IMỌLẸ OKUNKUN YIO PARADA IYẸN DAJU




BERE EGBOGI TUNTUN TI WỌN NPE NI:—

## "DROSELIA"

Meji rẹ kosi ni igboro Ilu Eko tabi Nigeria

Bi amodi "IKỌ" ti ọjọ rẹ ti pẹ tabi ti o ti to nkan bi ọdun kan tabi jubẹ lọ, awọn egbogi rebirọbi ti wọn nta kakiri tabi ipolowo ni orisirisi ko le se Iwosan rẹ rara, ma fi owo rẹ ṣe ofo mọ.

Bere fun egbogi awọn ara ilu Faranṣe ti nwọn npe ni "DROSELIA" o u owo haunhaun ati maiase egbogi fun Ikọ ẹgbẹ Ikọ Aiperi, Ikọ Awugbọn Ikọ Awugọn Iko ọnọfun, ikọ lile, ikọ ti o mọ ma enia tirin pẹlẹbẹ nigbakugba lati inu " Ifun wa (Lungs) tabi ikọ ti awulaogun lọsan tabi loru ti o si ma mu ki enia ma gbẹ ta bi iru lara pẹlu. Bi o ba dan Igo kan DROSELIA wo Iwọ na yio ri iyatọ ninu ara rẹ ni kiakia Igba aya rẹ ba ọna ọfun re ti o ma nho yio duro "IKỌ" rẹ yio sisan patapata iwọ yio si a jẹun daradara, iwọ yio si sun fọnfọn pelu, alafia de si ọ. Bere egbogi yi ati awọn ori ṣiṣi Egbogi Ikọ imran ni Ṣobu awọn:-

NIGERIA MEDICINE STORES
4 Tinubu Square Lagos

WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palmchurch Street Lagos
Phone 22878 (Oja Ita Faji)
ATI NI ṢOBU
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKEBỌLA
IBADAN

## 'UROYAN DRAGES'

Fun itọ tabi fifọ Apọ Ile Itọ (Kidney Blinder) fun ọkunrin tabi obinrin bi awọn amodi wọnyi ba nyọ ọ lẹnu orunkun, Ibadi, Gige tabi riro eri itọ, tabi itọ jijo enia iọ i un rukurusu Pipọn aisoleri itọ to lakuregbe orunkun owo ẹsẹ Ejika wiwu tabi riro.



Ara sisan, titobi ako le gbara konkan tabi kiakia didaji arinigbakugba ati orisirisi awọn aisan tabi amodi ba wọnyi ni egbogi ajẹbidan yi yio wo san lara rẹ ni kiakia ti alafia yio si de si ọ. Meji rẹ o si ni ilu Naijiria nitorina ṣọra ki awọn elẹtu tabi awọn oni robirọbi ma ta orisi omiran ti ko ni lari fun ọ, maṣe gba rara! Owo rẹ je Sile mẹfa abọ 6/6d owo Ọkọ sile kan ati abọ. (1/6d.)

NIGERIAN MEDICINE STORE
4 Tinubu Square, Lagos

# ..ọo Kan Fi Ponun Ma-
# .undinlogota Tanran

**IKEJA:-** Ni opin ọsẹ to koja lọ ni ri adajọ ile ẹjọ keke re ti Ikẹja kilọ fun ọdaran Oyinbo kan Jacob Harmer pe ti ko ba sọra nipa ori rẹ to ngmi niwaju on, o ni on yio fi iya to tọ ati to yẹ jẹ ọdaran na ti ile ẹjọ fi ẹsun kan pe o fi mọto rẹ pa ọmọ ọkunrin kan.

Adajọ ile ẹjọ na Ọgbẹni Adegoroye sọ eyi nigbati ọdaran na bẹrẹ si ni mu ori rẹ nigbati ẹleri fun Ijọba fi ọrọ rẹ ye ile ẹjọ lori ọna ti ọdaran Oyinbo na ti ṣe ala koso ni ile iṣẹ ni Ikẹja ti ṣe pa ọmọ na ti o bẹrẹ si ni mi ori lori ọrọ ti ẹleri na fi ye ile ẹjọ na.

Lẹsẹkẹsẹ ti ẹleri yi sọrọ ẹnu rẹ fun ile ẹjọ tan ni Agbẹjọro fun ọdaran na Ọgbẹni Okushipe fi ọro wa Ọgbẹni Adakẹ ti o jẹ Ọlọpa alamojuto oju ọna ti o si tun jẹ ẹleri ninu ile ẹjọ na ni o ti ṣe alaye ninu ọrọ rẹ pe on lọ sibi ti iṣẹlẹ naa ipe on si lọ won bẹ ibiti ọdaran na ti fi mọto pa ọmọkunrin na ki on to wa lọ si teṣan wọn.

Ọlọpa to jẹri nwaju ile ẹjọ na tun ṣe alaye pe ki iṣe oju on ni iṣẹlẹ na ti ṣẹlẹ bikoṣe wipe nigbati on gbọ ni o ohunti o ṣẹlẹ na ni on yara lọ sibẹ.

Gẹgẹbi ọrọ ti Ọlọpa na fi ye ile ẹjọ ni o ti ṣe alaye pe ọdaran Oyinbo na Jacob Harmer ti ṣe alakoso ni ile iṣura ti ibudo ọkọ ofurufu ti Ikẹja si fi mọto rẹ ti nomba rẹ jẹ LE 8627 pa ọmọ kunrin kan ti o fẹ kọja lọja ọna lojiji ti ko si wo ọtun wo osi ki o to gba oju ọna na koja eyiti Oyinbo na fi mọto rẹ koja ti o si ṣubu.

Lẹsẹkẹsẹ ti ọmọ na ti ṣubu ni Oyinbo na ba yara gbe lọ si ile iwosan ti Ikẹja eyiti o jẹ pe ko pẹ ti Oyinbo na gbe ọmọ na de ile iwosan na lo ba ku.

Ninu ọrọ ọdaran Oyinbo na ni o ti ṣe alaye fun ile ẹjọ pe on ti nwa mọto fun odidi ọdun marun sẹhin, o tun ṣe alaye pe on ti ri ijamba mọto fun igba diẹ ati pe ki iṣe ijamba mọto to pọ tabi pe ki on ti pa enia.

Ninu ọrọ agbẹjọro fun Oyinbo na ọgbẹni Okushipe tun fi ye ile ẹjọ pe ki ile ẹjọ ka da Oyinbo na silẹ pe ki o ma lọ layọ ati alafia nigbati awọn agbẹjọro fun ile ẹjọ na ti kuna ninu ọro won lati ri ẹsun kan to fidi mulẹ ti a le sọ pe nwọn fi kan odaran na.

O tun ṣe alaye pe otitọ ni ẹṣẹ na si jẹ ẹṣẹ kan to to eyiti o han si gbogbo enia loju pe ẹmi enia kan lọ ṣofo nipa ẹsun ti ile ẹjọ fi kan odaran Oyinbo na.

Ọgbẹni Okushipe tun rọ adajọ ile ẹjọ na lati gbe oye wo iru iwa rere ti ọdaran na hu gẹgẹbi ọmọ luabi ati pe lẹsẹkẹsẹ ti iṣẹlẹ na ti ṣẹlẹ lo ti yara gbe ọmọ na lọ si ile iwosan fun itọju ti o si tun yara pada bọ si ibiti iṣẹlẹ na ti ṣẹlẹ ti o si duro lẹgbẹ ti iṣẹlẹ na ti ṣẹlẹ titi ti awọn olopa fi de ibẹ lati wa ṣe ayẹwo ibiti mọto ti kọlu ọmọ kunrin kan. Agbẹjọro na si rọ Adajọ ile ẹjọ na lati ni oju anu rẹ si ọdaran na.

Agbẹjọro fun ọdaran oyinbo na tun ba awọn agbẹjọro fun ile ẹjọ na wi lọna ti nwọn ṣe kuna lati mu abayọri osi ti Dọkita ko sile lo iku ọmọ kunrin na eyiti o ṣe alaye awọn ọlọpa na ni lati mu wo si ẹjọ.

Ninu idajọ adajọ ẹjọ na na ni o ti ṣe alaye pe ọdaran Oyinbo na ni ẹjọ lati jẹ niwaju on ati pe ọdaran na jẹbi. Adajọ ile ẹjọ na tun ṣe alaye pe ki ọdaran lọ fi poun marundinlogota taran tabi ki o lọ fi ẹwọn oṣu mẹfa jura lafarabara.

---

## YE IRAWO RE WO

AQUARIUS (Jan 22 - Feb 20) Ohunti o daju gba ngba ni wipe ẹnikan yio wa bẹ ọ fun iranlọwọ. Oye rẹ ti iwo yio fi wo eluwarẹ ni yio jeki o mọ iru iranlọwọ ti o yẹ kio ṣe fun.

PISCES (Feb 21 - Mar 20) Ọpọlọpọ aye ni awọn o pe o si loni, nṣe ni ki o ṣọra ki o si fi han pe, iwọ ko nṣe iru eni ia bẹ

ARIES (Mar 21 - April 20) Nipa ọgbọn ati laaka ye ni iwọ yio fi ṣe ṣẹ ataki kan loni, oju rẹ yio la gbogbo iṣoro ibẹ yio si folọ

TAURUS (April 21 - May 20) Iwọ yio ri nkan ida mu die loni, maṣe jẹki ọkan rẹ damu, tun ero rẹ gba, iwọ yio si roju oire

GEMINI May 21 - June 21) Iwọ yio ri ere pupọ jẹ ninu iṣe kan ti iwọ yio ṣe, bi owo rẹ ba tẹ owo gbogbo yi na, maṣe fi jẹ bread ati Butter

CANCER (June 22 - July 22) Gbogba irawọ orun nṣadura fun ọ Bi o ba nfẹ iranlọwọ ki o sunmọ awọn enia ti o ri wipe nwọn ni lọwọ

LEO (July 23 Aug 22) Iwa jẹjẹ lo yẹ ki o ma hu, ki o si rin jina si ibi ti nwọn npariwo tabi ti nwọn nja ki o si dẹ oju rẹ sile iwọ yio ri nkan iyanu.

VIRGO (Aug 23 Sept 23) Iranlọwọ ti o ti nreti yio ti ọdọ enia re kan jade wa, ti ara rẹ han pe, ọkunrin ni o dajudaju nwọn o gbọ tirẹ.

LIBRA (Sept 24 Oct 23) Maṣe gbe ara re ga mọ lọ lati o kuro, ki o si jẹki ọkan rẹ ṣeran.

SCOPIO (Oct 24 Nov 22 Ig a rere yio si silẹ fun ọ bi ekoon a ba de, maṣe fi jafara.

SAGITTARIUS (Nov 23 Dec 21) Tete mura lati pari ija kan ti o ti wa nilẹ ki o si sin wo ẹjọ iwaju bi o tilẹ jẹ pe ko si owo lọwọ rẹ sile ki ṣe bi okunrin

CAPRICORN (Dec 22 Jan 21) Gbogbo gbogbo iṣẹ re loni maṣe beru bi enikan ba tọrọ ohun kan lodo re ra ki o mase ri jamba loni

---

## MO TUN GBE DE !



Ọgbẹni J. O. Shoyinka

Eyi ni lati tun sọ fun ẹnyin okawe wa wipe, Ọgbẹni J. O. Shoyinka abigegekubiejọ, Onitan Ajiran ilu awon oku, gbe t'ana danu, o tun gbe omiran de onitan yoyoyinyin yio tun beresi maa ko itan "MA FI OWURO ṢERE" sinu Iwe Irohin Imole lati ojo kini ose ti mbọ yi.

Itan na mu opolopo ogbon ati eko ijinle lowo ti o fi jẹ wipe, ko si omo Yoruba ti yio fe ki nwon rohin itan ala dun na fun on

Maṣe jeki nwon rohin itan na fun o, irohin ko to afojuba; ranṣe fun Iwe Irohin re ki o si ma je dodo itan.

Mase gbagbe, ose ti mbọ ni itan na yio jade.

OLOTU

## E Maa Ka Iwe Irohin Imọlẹ Lojojumọ

# Tani Nwọn Npe Ni Ọlọrun ?

## Lati Owo Ẹsọ

Ọdọmọde kekere-kan ti koju ẹni odun maruo lọ ti o si ṣẹṣẹ bẹrẹ ile Ẹkọ lati ma lọ pada de lati ilewe lọjọ kan bi o ti bọra silẹ tan o pe Iya rẹ, o wipe Mama Tisa wa ko wa ni iwe kan loni ko si ye mi, Nigbati ohunti o nwi ko ye mi rara mo wi ninu ọkan mi wipe, Mama mi yio fi ye mi daradara nitoripe Mama mi d gbọju Tisa wa lọ.

Mama Ṣọrọ fun mi ki mbula, ọmọ mi kini ohun na ti ko yẹ ọ?

Ọmọ Tisa wa a ma bere lọwọ wa bayi wipe Tani Ọlọrun? Awa a si ma da lohun wipe Ẹmi li Ọlọrun bi awa ko tilẹ ri ni on nri wa o mọ ohun gbogbo osi le ṣe ohun gbogbo Njẹ tani nwọn npe ni Ọlọrun na Mama?

Mama Ẹniti nwọn npe ni Ọlọrun mbẹ ni oke ọrun lọhun, on li o dia ẹmi, ati isẹ ati Baba rẹ on na li o si da Tisa rẹ ati gbogbo ohun ti iwọ le fi oju rẹ yi ati ṣugbọn enia bi awa yi ko le fi oju ri

Ọmọ Njẹ bi enia ba gbo ohun ti o ti bọjọ kuro nkọ Aki yio ha ri bi?

Mama Ko le ṣe gbe kuro, nitoripe gbogbo ẹniti o ba ni ẹran lara gẹgẹbi ti wa yi ko le ri ṣugbọn bi ọsan ati li oru on nri wa, o si li ni imọ ohunkohun tẹlẹ ki a to ṣe nkan na.

Ọmọ Mama mo fẹ ri Ọlọrun na nibo ni mo ti le ri Bi o ba sije wipe ni ilẹ Africa ni mo ti le ri nko kọ lati titori rẹ lọwọ iṣẹ atukọ oju o m i ti yio gbe mi lọ silẹ na nitori ki nlo ri.

Mama Ko nṣe nilẹ Afirka nkan ni Ọlọrun wa o mtẹ li ọ iọ wa nhin ati ni ibi gbogbo o si nwo mi bi mo ti mba ọ ṣọro rẹ yi o si tilẹ nfi rẹrin, Tabi iwọ ko gbọ ohunti o wi fun mi-nisisiyi?

Ọmọ Kini ohunti owi fun ọ Mama?

Mama O sọ fun mi wipe bi o ba di ni agogo meji la ọsan oni on yio yọju bi u sauma larin orun, ki o wa wo on nibẹ Inu ọmọde na dun de gongo tobẹ ti o bẹrẹsi sọ fun awọn ẹlẹgba rẹ k a k i r i wipe, on yio ri Ọlọrun loni,

Nigbati agogo mejila lu iya rẹ ile ti gbagbe o sare lọ bi iya rẹ nibiti ónṣe onjẹ o wi fun pe

Ọmọ;- Mama mama ago go mejila ti lu nisiyi wa fi Ọlọrun na han mi tabi o li o mbẹ ninu ọkọ ofurufu tio fo koja lọyi? Iya rẹ gbe oju soke ori wipe oru mu o pe ọmọ rẹ o wipe

Mama;- Ọmọ jade wa si hin nitori Ọlọrun tiṣi ferese ọrun sile fun ọ.

Ọmọ:- On da?

Mama; Ṣe Iwọ ri oorun ti o wa li oke, wo arin mẹi orun yẹn, iwọ yio ri ferese kan ti o ṣi silẹ, n bẹ ni iwọ yio ri ẹyi ju Ọlọrun ti yio ma rẹrin si ọ, tejumo ki o ma woo, yio si ba o sọrọ Ọmo na gbe oju soke, bi o si ti wo Orun, oṣubu lulẹ, o wipe

Ọmọ; Ye, ye, ye! mo ku o, oju mi fọ o!

Mama: Da a johun, o nju ọwọ si ọ

Ọmọ: O to! mama, nko tun wo mọ, o ma fọ mi loju ni?

Mama Njẹ iwọ ko ri i nisisiyi wipe ohun iṣoro li o jẹ fun enia ẹlẹran ara lati ri Ọlọrun,

Ọmọ: Bẹni Mama, mo gba nitotọ, pe Ọlọrun buru jojo

Mama: Bẹni nitotọ, o buru gidigidi fun awọn en a buruku, o si dara fun awọn enia rere. Nigbati o de ilewe ni ọjọ keji o rohin fun Tisa rẹ gẹgẹbi o tiṣe ri Ọlọrun si, Tisa ni ki o wa sọ niwaju awọn ẹgbẹ rẹ. Tiṣa na si kọ awọn ọmọ akẹkọ rẹ wipe ko si ẹniti o le wo oju Ọlọrun, nigbati iwọ ko le wo oju ọrun, bawo ni yio ti ṣoro fun ọ to lati wo oju Ọlọrun ti o da Oorun na

## Lati Oju Ewe Keji

Olotu: Hẹn O
Yẹyẹnatu: On lo rọ rudurudu saarin wọn
Olotu: O maṣe o. Nwọn ni ẹgbẹ na ti fọ si merin.
Yẹyẹnatu: O tilẹ ti fẹrẹ to mẹjọ
Olotu: Ha, yẹyẹntu ye purọ
Yẹyẹnatu: Odara ẹma binu
Olotu: Anu rẹ ṣe mi
Yẹyẹnatu: Suberu ni ki ẹ sa ba mi saanu
Olotu: Kini de ?
Yẹyẹnatu: Ṣe ẹ mọ pe wọn ti fi owo kun owo
Olotu: O ti o. Nwọn ṣẹṣẹ rọ pe ki ijoba fi owo kun owo wọn
Yẹyẹnatu: O dara, ani ki ẹ sa ba Suberu na wa iṣẹ tiṣa
Olotu: Bawo, ṣebi o mọ pe ko ni satifiketi fun iṣẹ tiṣa
Yẹyẹnatu Ṣe iyẹn? Iyẹn ko ṣoro kẹ
Olotu; Ani bawo ni o ṣe fẹ ṣe e ?
Yẹyẹnatu Ṣebi iwe ẹri ni mjẹ satifiketi ?
Olotu Yes, bẹẹni
Yẹyẹnatu Ṣe emi ko le jẹri pe Suberu mọ enia kọ ni? Tabi ẹnyin na ko ri awọn ọmọ ti nkọ ni lesson ti ngba tọrọtọrọ oṣu lọwọ wọn
Olotu Iru iwe ẹri bẹ kọ
Yẹyẹnatu;- Iru ewo ni Mag mago lẹ fẹ ko wọ
Olotu!- Rara. Bi o ba jẹ bi iwọ le ṣe tiṣa.
Yẹyẹnatu; O dun mi pe iru mi ko le ṣe tiṣa.
Olotu – Bawo ?
Yẹyẹnatu; Tiṣa obinrin melo ni ẹ ri ti o ma nkun ete bẹ emi ko le ṣe ki; nma fẹnu fọjẹ.
Olotu- Ṣe nitori iyẹn
Yẹyẹnatu Tiṣa obinrin melo ni ngbe run ẹran sori bi ajirin tiṣa obinrin melo ni nfi ḍan ati aiya silẹ ni titi? Awọn obinrin ti ko laju na ni nṣe tiṣa. Awa bayi ko lẹ ṣe tiṣa.

Olotu;- Yẹyenatu olotu o,
Yẹyẹnatu:- Yes kẹ Bi oyan wa ba si di rọbọ a le ra omiran ni kingsway bi idi wa ba wọle a le ra idi ni kingsway bakanna,
Olotu;- Ṣe olaju ni ẹnyin.

O dabọ


# Ogun Jẹdijẹdi

Aworan egbẹ yi fi han gbangba ibiti jẹdijẹdi to wa lara rẹ ti nyọ ọ lẹnu nigbagbogbo Ibẹ n a npe ni omusu tabi iho idi eniti ibiti ẹ ma ngba iṣe igbọnsẹ Arun Jẹdijẹdi jẹ ikan ninu amodi ti o buru, ni pataki fun okunrin ti o si ṣoro pupo lati ṣe iwosan rẹ tan patapata.

Ọpolọpo egbogi li owa tia nta kakiri ode isisiyi ti nwọn ma npolowo nwọn fun iwosan r e ṣugbọn boya ni a le ri mẹwa ninu awọn ogun to le ṣe iwosan arun na daradara.


CYCLOVEN

Awọn elomiran lero wipe boya bi wọn gbe lo si ile iwo san lati lo ge eyiti o ba nyo jade ni omusu on nipa bẹ awọn yio bọ lọwọ rẹ patapata.

Ṣugbọn awa koro bẹ rara lẹhin ọdun diẹ iyọnu rẹ yio si tun bẹrẹ bakanna Orişirişi Jẹdijẹdi ni o wa Ekini ti o bẹrẹ aiko maṣe Igbọnsẹ deede tabi lojojumọ, gigun kẹkẹ ologere Basikulu pupọ ẹlomiran ẹwu ẹran Siga oniruru ohun adidun pupọ, pupọju nigba kugba jẹdijẹdi orisirisi ni o wa ewo ni tirẹ? Bi o nyo sode ninu omusu tabi ti o ma nmu ẹjẹ wa lẹhin igbọnşe tabi ti nrin o ninu omusu rẹ ti o ba jẹ bẹ bere egbogi CYCOVEN ti awọn Oyinbo Jamani ṣeṣe wa idi rẹ ki o si dan wo o ri daju wipe Iwọ yio bọ lọwọ jẹdijẹdi patapata ti a ta nigboro Naijiria bere ni:-

WATERLOO MEDICINE STORE
8, Palm Church Street Lagos
Phone; 22878 Nigeria, Ọja Ita Faji

